# ONA TO LOSI ORUN

"Jesu wi fun u pe, Emi li ọ̀na, ati otitọ, ati iye: kò si ẹnikẹni ti o le wá sọdọ Baba, bikoṣe nipasẹ mi" (Johannu 14:6).

## IGBESI AIYE ENIA ATI ISERẸ

"Gbogbo wa si dabi ohun aimọ́" (Isaiah 64:6).
"Nitoriti kò si ìyatọ: Gbogbo enia li o sá ti ṣẹ̀, ti nwọn si kuna ogo Ọlọrun" (Romu 3:22, 23).
"Ọlọrun si ri pe ìwabuburu enia po pipọ̀ li aiye, ati pe gbogbo ìro ọkàn rẹ̀ kìki ibi ni lojojumọ" (Genesisi 6:5).

## IDAJỌ DAJU

"Niwọn bi a si ti fi lelẹ fun gbogbo enia lati kú lẹ̀kanṣoṣo, ṣugbọn lẹhin eyi idajọ" (Heberu 9:27).
"Njẹ nitorina, olukuluku wa ni yio jihin ara rẹ̀ fun Ọlọrun" (Romu 14:12).
"Awọn wọnyi ni yio si koja lọ sinu ìya ainipẹkun" (Matteu 25:46).
"Si ọrun apadi, sinu iná ajōku" (Marku 9:43).

## IYIPADA GBỌDỌ WA

"Bikoṣepe ẹnyin ronupiwada, gbogbo nyin ni yio ṣegbé bẹ gẹgẹ" (Luku 13:3).
"Bikoṣepe a tún enia bi, on kò le ri ijọba Ọlọrun" (Johannu 3:3).
"Bikoṣepe ẹnyin ba pada, ki ẹ si dabi awọn ọmọ kekere, ẹnyin kì yio le wọle ijọba ọrun" (Matteu 18:3).

## AWỌN IṢẸ KOLE BORI

"Kì iṣe nipa iṣẹ, ki ẹnikẹni má ba ṣogo" (Efesu 2:9).
"Kì iṣe nipa iṣẹ ti awa ṣe ninu ododo ṣugbọn gege bi ānu rẹ̀ li o gbà wa là" (Titus 3:5).

## IṢẸ KRISTI FUN ENIA

"Kristi ti kú nitori ẹ̀ṣẹ wa gẹgẹ bi iwemimọ́ ti wi" (1 Korinti 15:3).
"Ẹniti on tikararẹ̀ fi ara rẹ̀ rù ẹ̀ṣẹ wa lori igi" (1 Peteru 2:24).
"Eniti a fi tọrẹ nitori ẹ̀ṣẹ wa, ti a si jinde idalare wa" (Romu 4:25).

## IYEBIYE NI ẸJẸ KRISTI

"O si fẹrẹ jẹ́ ohun gbogbo li a fi ẹ̀jẹ wẹ̀nu gẹgẹ bi ofin; ati laisi itajẹsilẹ kò si idariji" (Heberu 9:22).
"Niwọnbi ẹnyin ti mọ̀ pe, a kò fi ohun ti idibajẹ rà nyin pada, bi fadaka tabi wura, kuro ninu ìwa asan nyin, ti ẹnyin ti jogun lati ọdọ awọn baba nyin, bikoṣe ẹ̀jẹ iyebiye, bi ti ọdọagutan ti kò li abuku, ti kò si li abawọn, ani ẹ̀jẹ Kristi" (1 Peteru 1:18, 19).
"Ẹ̀jẹ Jesu Kristi Ọmọ rẹ ni nwẹ̀ wa nù kuro ninu ẹṣẹ gbogbo" (1 Johannu 1:7).
"Nitoripe ẹ̀jẹ ni iṣe ètutu fun ọkàn" (Lefitiku 17:11).

## IPE KRISTI SI AWỌN ẸLẸṢẸ

"Ẹ wà sọdọ mi gbogbo ẹnyin ti nṣisẹ, ti a si di ẹrù wuwo le lori, emi o si fi isimi fun nyin" (Matteu 11:28).
"Ẹniti o ba si tọ̀ mi wá, emi kì yio ta a nù, bi o ti wù ki o ri" (Johannu 6:37).

## BAWO LAO SE GBA WA LA

"Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẹ̀ ge, ti o fi Ọmọ bíbi rẹ̀ kanṣoṣo funni, pe ẹnikẹni ti o ba gbà a

gbọ̀ má bà segbé, ṣugbọn ki o le ni ìye ainipẹkun" (Johannu 3:16).

"Gbà Jesu Kristi Oluwa gbọ́, a o si gbà ọ là, iwọ ati awọn ará ile rẹ́ pẹlu" (Iṣe awọn Aposteli 16:31).

"On ni gbogbo awọn woli jẹri si pe, nipa orukọ rẹ̀ li ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ, yio ri imukuro ẹ̀ṣẹ gbà" (Iṣe awọn Aposteli 10:43).

"Ati nipa rẹ̀ li a ndá olukuluku ẹniti o gbagbo lare kuro ninu ohun gbogbo" (Iṣe awọn Aposteli 13:39).

## BAWO LATIṢE LE SỌNU PATAPATA

"Awa o ti ṣe là a, bi awa kò ba nani irú igbala nla bi eyi" (Heberu 2:3).

"Ṣugbọn ẹniti kò ba gbagbọ́ yio jẹbi" (Marku 16:16).

"Eniti kò ba si gbà Ọmọ gbọ, kì yio ri ìye; ṣugbọn ibinu Olorun mbẹ lori rẹ̀" (Johannu 3:36).

## ONIGBAGBO NI IYE AINIPEKUN

"Ẹnikẹni ti o ba gbọ́ ọ̀rọ mi, ti o ba si gbà ẹniti o rán mi gbọ́, o ni iye ti kò nipẹkun, on kì yio si wá si idajọ; ṣugbọn o ti ré ikú kọja bọ si iye" (Johannu 5:24).

"Emi si fun wọn ni ìye ainipekun; nwon ki o si ṣegbé lailai, kò si si ẹniti o le já wọn kuro li ọwọ́ mi" (Johannu 10:28).

"Nkan wọnyi ni mo kọwe rẹ̀ si nyin ani si ẹnyin ti o gbà orukọ Ọmọ Ọlọrun gbọ́; ki ẹnyin ki o le mọ̀ pe ẹnyin ni iye ainipẹkun, ani fun ẹnyin ti o gbà orukọ Ọmọ Ọlọrun gbọ̀" (1 Johannu 5:13).

**Word Of Truth**, P.O Box 1126, Kaduna, Nigeria